# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

### Ose Ketadinlogun: Osu Kerin Ojo Kerinlelogun, 2016

### **Akori Oro: Idamewa** – Apa kini

### Eko Kika: Heberu 7: 1-10

## Afihan

Idamewa je ona ti a fi nfifun Oluwa pada lati inu opolopo ti o fi fun wa, sugbon o kereju o ni lati je idamewa ohun ti Oluwa fi fun wa ni a san, lati fi bojuto Ise Re ninu aiye. Iyato ti o wa larin idamewa ati awon ore ti o ku ni wipe enia nikan le da san idamewa tire ni igbati o wu tabi ki o san pelu opo enia fun awon ti Oluwa fun ni ase lati gba idamewa ni ibiti Oluwa ti pese lati gba idamewa.
E le fi idamewa sowo si ijo nipa leta tabi fi ranse lati owo enia, tabi ki a san sinu apo ijo ni ile ifowo-pamo; pelu adura wipe ki ibukun Olorun te siwaju ninu aiye wa nitori igboran ati sisan idamewa wa.
O dara ti enia ba ni igbagbo ti o jinle ti o si san owo ti o le die ni idamewa. Eyi ni yio fi idi re mule wipe iru awon enia be ni itara fun gbigboro ise Oluwa ni ile alaaye.

## Ibere Idamewa

Ibere idamewa ninu Bibeli ni igbati Abrahamu padabo ogun nibiti o ti lo gba Loti ati gbogbo ohun ini re sile lowo awon ti won ko ni igbekun. Olorun fi si okan Melkisedeki oba Salemu eniti o mu onje ati oti waini wa fun Abrahamu ni ipadabo ogun. Melkisedeki si sure fun Abrahamu wipe "Ibukun ni fun Abrahamu, ti Olorun oga-ogo, eniti o ni orun on aiye. Olubukun si ni Olorun oga-ogo ti o fi awon ota re lee lowo."
Abrahamu nipa imisi Oluwa si da idamewa ohun gbogbo ti o ko bo lati oju-ogun fun Melkisedeki. Isele yi ki se ohun ti o dede sele tabi ohun ti o se konge, bikose nipa ipinu ati imotele Olorun wipe awon iru-omo Abrahamu yio ma se igbese sisan idamewa titi lailai.
Ohun ti Abrahamu se yi tumo si wipe ao ma bojuto ailera ati aini awon alufa/iranse Oluwa lati inu idamewa ti awon enia ba nsan, ni iwon igbati won koni ise miran ju ise Oluwa lo.
Tori idi eyi ni Olorun se npese fun won nipa idamewa ti awon enia ba san, ki inu won ba le dun ki won si le se ohun gbogbo ti won nilo lati se **Genesisi 14: 16-20; Heberu 7: 1-4.** San idamewa re loni ki ibukun Olorun le jeyo ninu aiye re.

## Jakobu je eje o si san idamewa re

Jakobu ni eni-tokan ninu eto Olorun nipa idamewa, toripe eleyi ni o jogun ibukun/ileri Abrahamu **Genesisi 28: 11-15**. Jakobu je eje atokanwa fun Olorun ni igbati o sa kuro niwaju Esau egbon re.
O je eje wipe "Bi Olorun ba pelu mi, ti o si pa mi mo ni ona yi ti emi nto,ti o si fun mi ni ohun jije ati aso bibora. Ti mo si padawa si ile baba mi ni alafia; nje Oluwa ni yio ma se Olorun mi. Okuta yi, ti mo fi lele se owon ni yio se ile Olorun: ati ninu ohun gbogbo ti iwo o fi fun mi, emi o fi idamewa re fun o **Genesisi 28: 18-22.**
Lehin isele yi idaduro ranpe wa nipa sisan idamewa toripe Jakobu ko so fun awon omo re nipa ire ti o wa ninu ki enia je eje ki o si san eje re. Jakobu pa enu re mo nipa awon ibukun ti o ri gba lati odo Oluwa ni igbati o san idamewa re, eyiti o le je ohun iwuri fun awon iru-omo re lati tele awon isise re **Genesisi 35: 1-7**. Sugbon ni igba aiye Mose ni oro idamewa wa di ilu-moka.

## Ko si odi fun awon alufa/iranse Oluwa

Olorun nipa ogbon re ti enikeni ko le sawari pase fun Mose wipe ki o mase fun awon omo Lefi ni ile-ini larin awon omo Israeli. Ipinu yi ki se nitori a korira won, sugbon o je nipa imo Olodumare ki ise/oro re o ba le tan-kale origun mererin ile Kenaani (Ile Ileri) ni.
Ti o ba je wipe a fun awon eya Lefi ni ile-ini ni, awon wonyi iba korajo po sori ile-ini won ni; ni ona ti yio jeki ise/oro Olorun gbile ni apakan gbogbo agbegbe na. Ni iwon igbati a ko fun won ni ile-ini, won ngbe ni ibi gbogbo ni ile Israeli, won si nse ise ninu tempili; ti won si ngba idamewa ni owo awon omo Israeli elegbe won, ninu eyiti o mu ise/oro Oluwa gbile jakejado ile Israeli.
Awon omo Lefi ni o ni gbogbo ebo igbesoke ti awon enia ba muwa fun Oluwa ati idamewa.Eyiti o tumo si wipe eyi ni ipin won, tori re si ni Oluwa se wipe won ko gbodo fun won ni ile-ini larin awon omo Israeli **Numeri 18: 24.**

## Idamewa je ajemonu awon omo Lefi

Olorun yan eya Lefi larin awon eya mejila Israeli lati ma se ise-isin ago ajo. Oluwa fi awon eya Lefi fun Mose gegebi ebun, lati ma kun Mose lowo se ise Oluwa ninu ago ajo **Numeri 18: 6**. Amo Olorun san won ni esan fun akitiyan ati laala ise-isin ti won nse ninu ago ajo nipa fifi gbogbo idamewa ti a ba gba jakejado ile Israeli fun won.
Eyi tumo si wipe, awon alufa/iranse Oluwa nikan ni o leto ati gba idamewa ni owo ijo Olorun; ni igbati ao si ma san owo osu won lati inu idamewa yi **Numeri 18: 21; Heberu 7: 5.**

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Idamewa owo osu re, ti Olorun ni

Iru enikeni ti o le je, iru isekise ti o le ma se ati iru ipokipo ti o le wa larin awon omo adari-hurun; ojuse re ni lati san idamewa re. Mase gbagbe wipe idamewa ohun gbogbo ti o ni ninu aiye ti Olorun ni; torina awa kristiani ni lati faramo sisan idamewa pekipeki, ki a ma ba jebi ni iwaju Olorun.Ni iwon igbati o je ase Oluwa ni, e jeki a san idamewa owo-osu/ oko-owo/ebun/ere-oko ati be be lo **Lefitiku 27: 30-32.**

## Awon Alufa/Iranse ni lati san idamewa

Ni igbakugba ti awon alufa/iranse ba gba idamewa, ase Oluwa ni pe won gbodo yo idamewa ipin na, ti awon pelu yio san gegebi idamewa tiwon. Eyi tumo si wipe awon alufa/iranse ko bo lowo sisan idamewa, torina won ni lati san idamewa ninu idamewa ti a ba fi fun won **Numeri 18: 26; Heberu 7:9.**

## Idamewa ko yo awon alabojuto sile

Awon Alufa/Iranse/osise gbodo san idamewa fun alabojuto ijo, ninu eyiti on na yio mu idamewa re lati fifun awon omo-orukan/opo/sise alejo ati ise Olorun.
Awon enia ti alabojuto ba pin idamewa fun gbodo san idamewa ohun ti a pin fun won sinu ijo tabi fun awon alufa/iranse, ki ohun gbogbo le ma lo dede. Ni iwon igbati Olorun je olori gbogbo awon onimo-ijinle, o se oro idamewa yi ni aditu ki odada owo/ire maba da ijo re ati pelu ki gbogbo enia le ri owo mu losi enu **Numeri 18: 28.**

## Ibiti a ti gbodo san idamewa

Ile esin ti Oluwa ba yan, ni ibiti a ti nbowo fun oruko mimo re nikan ni Kristiani ti gbodo san idamewa. Nitori akoko ti ko ba enia se ore ati awon ohun miran ti o le sele, enia ore-ofe lati fi idamewa re sowo nipa leta,tabi fi ranse lati owo enia, tabi san si apo ijo ni ile ifowo-pamosi ki ore re ba le se itewogba **Deuteronomi 12: 5-6, 11, 17-18.**

## Rira idamewa pada

Enikeni ti o ba fe ra idamewa eso/ohun osin tabi ti ohunkohun ti o je mimo fun Oluwa pada, nitori idi pataki kan, ni lati fi idamarun kun iye owo re. Boya o je aagbe ti ona ibiti Oluwa yan jina fun o lati ko ere-oko re wa lati san idamewa re; iyekiye ti o ba ta ere-oko na o ni lati fi idamarun kun ni bibeli wi **Lefitiku 27: 31.**

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

### Ose Kejidinlogun: Osu Karun Ojo Kini, 2016

### Akori Oro: Idamewa – Apa keji

### Eko Bibeli: Heberu 7: 1-10

### Awon Ayorisi Ai-san Idamewa

Gbogbo okan ti ko ba san idamewa re ni akoko je adigun-jale, toripe won nja Oluwa ni ole nipa aifi eto re fun. Won hun se Oluwa nipa fifi ipin ti yio mu itesiwaju ba ise re ni ile alaaye dun. Nitori ese nla yi, iru awon enia be ko le ri ore-ofe ati anu kikun gba lowo Oluwa. Ni afikun, won yio pari irinajo won si odo Satani.
Lotito sisan idamewa ati ore nikan kole mu enia wo ile-ologo, ayafi ti enia ba gboran si awon ase Oluwa ti o si pa awon ilana re mo. Sugbon sisan idamewa re ni akoko yio jeki Oluwa:

- Bukun o, iwo yio si ni anito ati ani-seku ibukun.
- Fi opin si ogun agbana, ogun asare-pe ati inawo ojiji ninu aiye re.
- Fi idi ase isodi-pupo mule ninu aiye re ni ona ti yio jeki idamesan ti o ku si o lowo to lati gbo bukata re, ti o ki yio fi kabamo wipe o san idamewa **Malaki 3: 8**

Lati oni lo san idamewa re ni akoko ki o si dekun ati ma ja Oluwa l'ole, ki ayipada otun ba le jeyo ninu aiye re.

Awon enia ti won ko san idamewa won nre Oluwa je besini egun Oluwa nbe lori won. Egun yi ni nfi aye gba esu lati gbe koto agbana ti o fi nko ere ise won lo.
Egun ai-san idamewa ni o nja opolopo onigbagbo agbaye. Opolopo awon olufokansin ni aiye won wa lojukana ti kosi si ilosiwaju nitori idi yi. Awon Kristiani kan tile ti so idamewa di eje, ti o je wipe won yio je eje ti won yio si san iye ti o rorun fun won lati inu owo-osu/oya won nipo idamewa. Eleyi ko se itewogba niwaju Oluwa.
E jeki o ye wa daju wipe bi enia tabi edakeda ba gbe o gbegun, Olorun yio paare, sugbon bi Oluwa ba gbe o gbegun tani yio ba o we sonu. Ni opo igba egun ai-san idamewa ki jasi iku, sugbon o nfa opolopo nkan ti a o mu enu ba:

- Ogun aini ohun amu-yangan ati kose-mani ni yio ma ja aiye onitohun.
- Ire ati ibukun yio sowon ninu aiye eda be.
- Oda ayo ati ohun rere ti o le muki o soro fun ero-ngba okan be lati wasi imuse yio ma sele.
- Ogun aito ti nda enia ru yio gbile ninu aiye eni be. **Malaki 3: 9.**

Ara e mase darapo mo awon Kristiani ti ki san idamewa rara tabi awon ti ki san pe. Iru awon iwa yi ni nmu egun Oluwa wa, o ndena igbega besini o nmu ki ati te siwaju ninu aiye je inira ati isoro.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Awon ere sisan idamewa

Olukuluku okan ti o ba san idamewa ati ore won ni akoko yio ni itura ni igba aiye won , iru awon enia be ki yio se eru owo, toripe asiri won ki yio tu besini won yio lu aluyo nipa owo. Pataki-julo ti won ba le san ohun ti o le die ni idamewa won awon ileri yi yio wasi imuse, amo eyi ko tumo si wipe won yio wo ile ologo.
Ibukun Oluwa yio bori iru awon enia be ao si bukun fun won ni ona ti o koja oye won. Iru ibukun be ki se ti owo/oro nikan yio je ti alafia, ara pipe ati emi gigun **Malaki 3: 10.**
San idamewa re loni ki o si ri bi Oluwa yio ti si ferese orun fun o ti yio si r'ojo agbonmagbe ibukun ti nderuba osi le o lori eyiti aye ki yio si lati gbaa.

## Idamewa Ti Kose Itewogba

Awon idamewa ti a ba san lati inu awon ona ti ao menuba yi ko se itewogba ni iwaju Oluwa:

- Owo eje
- Oya agbere
- Owo ti a ni nipa jibiti/ona aimo
- Idamewa ti a san nipa ikunsinu/afipase

## Gbadura Ki O To San Idamewa Re

O se pataki ki a gbadura ki a si ran Oluwa leti ni igbakugba ti a ba nsan idamewa wa lati fun wa ni ere nitori igboran, idurosinsin ati otito wa. Gba adura si Olorun ki o fun o ni ibukun Abrahamu, ki o si ba ajeni-run ati apani-run wi ninu aiye re.
**Deuteronomi 26: 12-15, Malaki 3: 11.**
Oluwa ti o rii, ti o si mo wipe o san idamewa re ni ikoko yio bukun fun o ni gbangba besini ire ti ko sele ri ninu iran re yio farahan ninu aiye re.

## Awon Idi Ti O Fiye Ki A San Idamewa

Nigbati awa olufokansin ba san idamewa wa ni itura yio deba awon alufa/iranse Olorun, ti awon na yio si le se ise won ni ai-si iberu, ojusaju, aisododo ati iwa ibaje. Amo ti awon ara ninu Oluwa ba ko lati san idamewa won, koni si owo ti yio to lati bojuto aini awon alufa/iranse Olorun ati lati pese fun won ni kikun. Ti iru eyi ba sele awon ijo Olorun na yio pin ninu ebi esekese ti awon alufa na ba se si Oluwa, nitoripe won mo ohun rere lati se sugbon won kuna lati se e.
Nipa iru iwa yi awon ijo na ti se aigboran si ofin Oluwa ni ona ti o muki awon alufa se asise ni iwaju Olorun. **2 kronika 31: 5-12; Nehemiah 13: 11-12.**
Ara ninu Oluwa e mu idamewa yin wa si ile Oluwa ni akoko, ki Oluwa le bukun fun

yin ni ona ti e ko lero ati ki awon alufa le ni anito ati aniseku onje.

Esin kristiani yio tun-bo dara si ti awon olufokansin ba le se ipinnu lati ma san idamewa won gegebi awon omo Israeli ti se san idamewa won ni igba Nehemiah **Nehemiah 10: 35-38.**
San idamewa re ki ile Oluwa ma ba se alaini awon ohun ti o se koko tabi mo iyan ohun ti o dara. Ni igbati o ba pinnu ti o si san idamewa re ni akoko ni Oluwa yio san esan ise rere re nipa fifi ohun ti okan re hun pohun-gbe fun o, ti awon ala rere re yio si wasi imuse.

**Idamewa Gbodo Je Kedere**

Awon enia ti o wa ni idi gbigba idamewa gbodo je olotito ati eniti nse ohun gbogbo ni kedere. Won ko gbodo je onibaje enia ti won le kowo-je tabi ki won je oni-jibiti ti won le yi-we iye owo ti nbe ninu apo idamewa nitori ojukokoro won.
Won ni lati mo wipe Oluwa ni won nsise fun kise enia. Oju Oluwa si nwo awon nkan ti awon enia na nse lati san won ni esan ni igbati akoko ba to, fun gbogbo ise ti won ti se yala rere tabi buburu. **Nehemiah 12: 44, 13: 3-5.**
E je olododo ati eniti nso oju-abe niko nipa gbigba ati pipin idamewa. E mase lo iwa ojusaju tabi agabagebe ki o ba le dara fun yin.

Igbati a ba fi gbogbo ola/oro wa **bowo** fun Oluwa pelu gbogbo ohun-ini ti a ni ninu aiye yi, nigbana ni Oluwa yio kun aiye wa pelu ayo ailopin, yio fifun wa gegebi ero okan wa ni rere, besini aiye wa yio kun akun-wosile pelu ire Olorun. **Owe 3: 9-10.**
Ranti wipe Oluwa ni o ni kokoro aiye re atipe ohun gbogbo ti o ni kise nipa agbara tabi mimo-se re sugbon nitori ore-ofe ti o ri gba lati odo Oluwa ni.

Ni akotan, ofin Oluwa ni fun gbogbo okan lati san idamewa won. A ni lati san si ile-ijosin ni ibiti Oluwa yan ti a si nbowo fun oruko re nibe. Ti iru ibiti Oluwa yan yi ba jina ju tabi ti o ni isoro oko lati ko idamewa re, o le yipada si owo. Amo o je oro-yan fun awon olufokansin lati tele ilana yi. Ti o ba se aigboran si Oluwa nipa ai-san idamewa re, eleyi yio fi aye gba esu lati lo asise yi gegebi ategun lati mu ki aiye re polukuru-musu.